# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA
No. 600 FRIDAY MAY 8, 1964 (2D)

## Ọdaran Kan Fọ Ọlọpa L'ori !

KANO:— Malam Adamu Tassawa, adajọ kotu Ijọba Ibilẹ Kano ṣe idajọ pe, ki Ọdaran ọdọmọdebinrin kan, Omidan Magajiya Dambatta, ẹni ọdun mọkandinlogun lọ fi ponun mẹwa (£10) tanran si kotu tabi ki o lọ fi ẹwọn ọgbọnjọ jura nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa mu fun.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye niwaju adajọ pe, ni ọjọ kọkanlelogun oṣu ti o kọja yi ni Ọdaran na lọ si ile ero kan, "Niger Club" lati lọ gbadun ara rẹ.

Ṣugbọn nigbati o de ile-ero na, ni ija ba de larin on ati awọn kan ninu ile ero na ti nwọn si bẹrẹsi ja, ti gbogbo awọn ti o wa jẹun nibẹ fi sa jade ti nwọn si binu fi ile-ero na silẹ.

Ṣugbọn nigbati Ọlọpa kan, Alli Mada de, ti o si la awọn enia na pe ki nwọn o maṣe ja mọ, Ọdaran na ko gbo okuta kan ti o mu nilẹ,. lo ba gbe soke o si sọ fun Ọlọpa na pe, "Maa lọ kuro larin wa" lẹsẹkẹsẹ ni o la okuta na mọ Ọlọpa lori,ti ori Ọlọpa na nṣẹjẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ba mu Ọdaran na, nwọn si gbe Ọlọpa na lọ si ile Iwosan fun itọju. Nigbati Ọdaran na rojọ, ti o si gba pe, on jẹbi, ni adajọ ba fi ṣe idajọ gẹgẹbi a ti wi ni oke iwe yi.

**Adebiyi Sọ Pe :**

# JAKANDE KO KỌ IṢẸ OGUN NI GHANA

EKO:— Gbẹgẹdẹ gbina ninu ile ẹjọ gigajulọ fun orilẹ-ede yi ni Eko lana nigbati Ọgbẹni Duro Adebiyi, Abanirojọ pataki fun Apapọ Ijọba Naijiria nsọ niwaju ijoko awọn adajọ mẹrun wipe Ọgbẹni L. K. Jakande jẹbi ẹsun ti adajọ ju ṣẹwọn fun nitoripe on lo san owo fun awọn enia kan ti nwọn sọ pe nwọn lọ si Ghana lati lọ kọ iṣẹ ogun, eyiti nwọn fẹ fi doju Ijọba bolẹ.

Ọgbẹni Adebiyi ṣe alaye pe, Ọgbẹni Jakande ni o mbere ọrọ lọwọ awọn enia na ti o si nfun wọn lowo lati lọ si Ghana, gẹgẹ bi ẹri ti Patrick Dokotri wa jẹ niwaju adajọ.

O wa ṣe alaye pe, adajọ Agba Ṣowẹmimọ jare ẹjọ ẹwọn ọdun mẹ'e ti o se fun un, ṣugbọn bi o ti nsọrọ yi lọwọ ni Ọlọla Adetokunbọ Ademọla gba ọrọ na ma lẹnu.

Ademọla: 'Ṣe owo ti Jakande san lo mbi ọ ninu? nigbati o jẹ wipe ọkan ninu awọn eegun ẹhin ni o jẹ fun ẹgbẹ. Kini ohun ti o o fẹ ki o ṣe? Iṣẹ ti nwọn ran lo nje" Brett: "Ninu ẹṣẹ meji ti nwọn fi kan an; nje lori ẹsun yi ni adajọ ṣe ṣe idajọ ẹwọn fun un?"



Ọgbẹni 'Duro Adebiyi
*Agbẹjọrọ Ijọba*

Ademọla: "Nje ti ẹnikan ba nlọ si idalẹ ti o si fẹ wọ ọkọ reluwe ti o ba gbe ẹru rẹ fun alaru, to si jẹ wipe ẹniti nlọ si idalẹ ji ẹru na gbe ni, nje nwọn le mu alaaru na pe, o gbimọpọ pẹlu ẹniti o ji ẹru ki nwọn si mu alaru pẹlu ole ti o fẹ wọ ọkọ nigbati o jẹ wipe iṣẹ alaru ni alaru nṣe ?"

Ọgbẹni Adebiyi wa pe akiyesi awọn adajọ si ẹjọ ti Olearl ati Anthony Oboh ro niwaju adajọ ni oju iwe ọgọta (page 60) pe Jakande lo ran awọn enia na pe ki nwọn lọ gba iwe aṣẹ irinna ki nwọn si mura lati lọ si Ghana.

O tun ṣe alaye pe awọn enia na wa ninu ipade ti awọn kan ṣe, nibiti nwọn ti sọ fun wọn pe ki nwọn mura lati wa ni abẹ aṣẹ Ọgbẹni S. G. Ikoku.

O tun wa pe akiyesi awọn adajọ si ẹjọ ti Dokita Maja ro nile ẹjọ nibiti Dokita Maja ti sọ wipe on ri Ọgbẹni Jakande pe on nlọ ra awọn ohun ọṣẹ ni Ghana, ṣugbọn o ṣoro lati gbewale ninu ọkọ oju-omi.

Lẹhin eyi, Ọgbẹni Adebiyi tun sọ siwaju pe, Maja tun sọ fun Jakande pe, on (Maja le ri awọn nkan ija ogun ra ni Abẹokuta lọdọ ọrẹ on kan ti orukọ rẹ nje Adedipẹ, ni toripe iṣẹ alakuta ni o nṣe.

Oni Dokita Maja tun ṣe alaye fun ọgbẹni Jakande pe onti fi ẹdẹgbẹta ponun tabi ẹdẹgbẹrin poun (£500) tabi (£700) ranṣẹ si Adedipẹ ni Abẹokuta lati ba on ra awọn ohun ija ogun na.



Oloye Awolọwọ

Lẹhin opolopọ ibere ati alaye ọgbẹni Adebiyi pari ẹjọ rẹ bayi pe.

"Oluwa mi, mo gba daju pe, nitootọ ni Jakande ṣẹ ẹṣẹ ti adajọ ju ṣẹwọn si, mo si sọ fun nyin pe, ki ẹ maṣe gbọ awijare rẹ, ẹ jẹki o jiya ẹṣẹ rẹ"

Ọgbẹni Duro Adebiyi ni on gbagbọ wipe owo ti Jakande san fun awọn enia na ki iṣe owo Allied Newspapers "bi ko ṣe owo ẹgbẹ Afẹnifẹre"

O ni on mọ wipe Jakande kolọ si Ghana fun ẹkọṣẹ ogun, ohun ti o lọ si Ghana fun yatọ ṣugbọn Olearl sọ pe, o sọ fun on pe, ti on ba wọ inu mọto ki on maṣe ṣe bi ẹniti o ma on, ti on ba de ile ni ki on wa ri on.

Ṣugbọn ki o to sọrọ yi delẹ, ni Ọgbẹni Olu. Ayọola dide lori aga idajọ rẹ to si sọ wipe, irọ ni Ọgbẹni Adebiyi pa, ko si ohun ti o jọ

Wo Oju Ewe Kẹfa



Latifu Jakande



Ọlọla Ademọla
Olori Awọn Adajọ

**Nje Oke—Iṣoro wa fun Ẹ Bi ?**

FUN IWADI OHUNKOHUN KOWE SI WOLI

D. Abiọdun,
P. O, Box 1554,
Lagos, Nigeria.

Jọwọ fi Stampu tọrọ eti address rẹ ranṣẹ si wa lati tete da esi pada ni kiakia.

# Iṣẹ Awọn Iwe Irohin Larin Ilu

Ninu awọn iṣẹ ti o ni iyin ti o si ni isiri ohun pupọ larin ilu iwe Irohin jẹ ọkan pataki ti o ni iṣẹ ribiribi lati ṣe fun itọni fun ẹkọ ati lati mu ki ilu dagba ṣoke iwe Irohin jẹ ọkan pataki ti o ntan imọlẹ si nu ọkan t ṣokunkun, o ran ọpe lọwọ lati di onimọ bakanna ni o ntọ alaini mimọ pupọ si ọna ominira.

## Lati Ọwọ S. O. Jaiye

O si nsọ alailagbara di akọni nipa fifi ọna to tọ han. Gẹgẹ bi imọlẹ ti nwa lati orun ti o si fun ni oru ti o mu eweko dagba bẹni Iwe Irohin larin orilẹ ede kan si ekeji.

Laisi Iwe Irohin larin ilu gbogbo igbokegbodo awọn enia ko ni mu iwuri ati ilọsiwaju wa si arin ilu.

Gẹgẹ bi awọn olukọ i ti nfi ọna han Ọmọ Ile-iwe bẹ ni Iwe Irohin ntọka si awọn alebu to wa larin Ilu.

Nigbati ilu ba parọrọ Iwe Irohin ni anfani pupọ lati ji olokuluku kuro ni iparọrọ.

Iwe Irohin larin ilu o jẹ ohun iranlọwọ pupọ fun ijọba Eyi ni pe ti Ijọba ba fẹ ṣina tabi fẹrẹ ma sun, Iwe Irohin jẹ ohun alore lati ji Ijọba loju orun.

Bi oluṣe buburu ba wa larin ilu Iṣẹ Iwe Irohin tun wa fun iranlọwọ lati fi igbe ta fun iwa aidọgba larin ilu nipa bayi oluṣe buburu na a yipada kia fun rere bi ko ba si yipada awọn enia yio mọ iru ẹni bẹ nitori na nwọn mọ ọna ti nwọn yio ma yago tabi sa fun ẹni bẹ fun idi eyi Iwe Irohin tun wa lati tun igbesi aiye Ọmọ enia ṣe dada.

Orişirişi iwe Irohin lo wa omiran wa lati m rohin ohun to ṣẹlẹ lar n ilu lojojumọ, omiran wa ti yio ma ṣe akopọ irohin lọsọsẹ ati lọsọsu omiran wa lati ma fi kiki aworan han bi aworan arẹwa Obinrin tabi Ọkunrin.

Bakanna omira wa lati fi bi papa tabi ọdan, oke tabi pẹtẹlẹ, igbo tabi iju, odo ati awọn oke han omiran wa lati ma fi awọn ile nlanla ilu han larin ilu.

Bi Iwe Irohin ojojumọ ti ṣe wa bakanna ni awọn Iwe Irohin nipa oniṣegun tiṣe wa iwe Irohin lori Ina onimanamana wa ati Iwe Irohin lori ọja tita na tun wa, O fẹrẹ ma si iṣẹ kan ti ọmọ enia nṣe ti Iwe Irohin ko ni ọwọ ninu rẹ,

### AWỌN OLOTU

O fẹrẹ ma si ohun rere ti Iwe Irohin ko le mu wa si arin ilu ṣugbọn ohun pataki kan wa ti o ni akiyesi pupọ.

Bi iwa awọn to jẹ olotu Iwe Irohin ba ti dara to ni Iwe Irohin wọn ma ndara si Bi Olotu Iwe Irohin na yio ma han nipa ohun rẹ larin ilu

Ninu awọn ohun to ṣe pataki ninu Iwe Irohin nipe awọn kan wa ti o ṣe pataki ninu iṣẹ yi awọn to wa ni idi erọ itẹwe awọn to nto awọn ọrọ sori erọ itẹwe awọn ti o nse atunka iwe ti ati tẹ,

Ẹnikan ninu awọn ti mo daruko loke iwe yi ni lati jafafa ninu iṣẹ ti a gba wọn si Ko yẹ ki ẹniti o wa ni idi erọ mọ iṣẹ rẹ tan ki ẹniti nto iwe sori erọ ma se dada to.

Bakanna awọn ti o nse ayẹwo awọn iṣẹ iwe titẹ ki o ma mu na rara gbogbo wọn ni lati ṣe bi iti apapọ oniṣẹ kan. Bakanna iṣẹ olotu Iwe Irohin jẹ iṣẹ pataki lati ma ṣe ki iwe rẹ yio ti ma jade lojojumọ.

Olotu ni ẹniti o wa di agba ibọn mu. Ko gbọdọ sun tẹtẹlẹ tẹ. Nitori ohun kohun ti o ba jade ninu iwe irohin rẹ to ba lodi si ofin Ijọba tabi ki a sọrọ ẹnikan n bi on ni ẹniti a ni lati gbamu fun ẹsun ọrọ na.

### IKUNA

Nitori na olotu Irohin ni lati ja fafa. O sini lati mọ awọn ofin pẹpẹpẹ to so mọ iwe Irohin. Ki a ma ba gbaa bi bọlu kiri ninu ile ẹjọ. Olotu ni lati ni olumọran amofin.

Ninu iṣẹ iwe irohin yi awọn oludari iṣẹ iwe irohin ati baba isalẹ ni lati fun awọn eto idagbasoke iṣẹ yi ati gẹgẹbi iṣẹ na ni lati mu ere wa le.

Fun aimọ eto aimọ ero ni iwe na ṣe kuna Ti gbogbo awọn ti nşişẹ ninu ile iṣẹ irohin ba wa ni idi kan ninu iṣẹ wọn iyọnu ko ni si fun wọn rara.

Bi iwe irohin ti ṣe jẹ iṣẹ to dara to ti o si le fun enia ni ọlẹ bakanna ni iwe irohin e rẹenia silẹ larin ilu. Loni apa yi ni awọn ti o nlọ ka kiri lati ko irohin jọ pọ fun olotu lati ṣe apero lori aṣajọ ni ọnyi,

Bi mo ti sọ ṣaju ko si ohun ikọkọ ti iwe Irohin kole yọ jade. Ninu igbona igbo u ogun ati ọtẹ iwe irohin wa.

Ninu ohun gbogbo ti o jẹ ayọ ati ẹrin Iwe Irohin wa nibẹ lati ba ni yọ, Ninu ẹkun ati ariwo iwe Irohin wa lati sọ idi ẹkun na,

Ninu ojo ati oru ninu ati oşupa ninu idakẹrọrọ ati ilu pẹlu ijo gbogbo Iwe Irohin wa nibẹ fun alaye gbogbo nkan fun ni.

Pari ohun gbogbo fun idagbasoke Iwe Irohin ni agbara lati ran ilu lọwọ lati tun ilu ṣe lati ba ilu jẹ lati mu ki ere wa ninu iṣẹ bakanna o tun le fa adanu ba iṣẹ ẹni.

Lati mu ki irẹpọ wa larin ilu lati mu ifẹ ninlẹ larin orile-ede aiye. Iwe Irohin ni ipa pupọ lati sa.

Wo Oju Ewe Karun


make it a successful
SEASON
with MERCEDES BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

# IWE SI OLOTU

## Alhaji Disu, Ẹ Sọ Eyi ?

Olotu, e gba mi ni aye ninu iwe IROHIN IMỌLẸ ti o njade lojoojumọ fun anfani awa ti a ko mọ ede Oyinbo ka daada, iwe na nkọ wa ni ọgbọn ati oye, o si nfi ede Yoruba kọ wa daada.

Nigbati mo ka ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ kejidinlogun osu kerin ninu ọdun yi pe nwọn le are ẹyọ lati ẹnu Alhaji Y. A. Disu ti e si gbe aworan Oloye Coker si pelu.

Ọrọ na dabi ala loju mi, niteripe ẹniti o kọ ọrọ na na Alhaji ni ti o mo wipe Oluwa ko fẹ oriṣa rara.

Bẹni lọsan; loru ati nigbogbo igba ni awọn Imble nkigbe pe, ki Ọlọrun pa pana Keferi ki a mọ si ṣe gburo ni riwa bẹ mọ rara, iou Ọlọrun ko dun si iwa ẹ ara, Mo si lero pe, Alhaji Disu io ọkan ninu awọn ti ko fẹ ki sin Iborisa mọ gbilẹ si lami ilẹ.

Owa jẹ wipe awọn to ni iberisa ko dara to na ni o tun nsọrọ ẹyọ fun wa gbọ, abi ẹyọ fun wa pọ, abi ẹyọ kiṣe oriṣa? Ko tọ ko yẹ ki atun mẹ ba ẹr oriṣa lẹuu oru Alhaji bi ti wọn mọ rara.

Awa ti a nṣe ofin ni ni a tun ntuu, ati mọ pe, awọn ọm Imọlẹ ni o ngbe ẹyọ na' asiiko to ti ro kilo fun

Emi ni,
A. A. E Boye
EKO.

## Ero Mẹkka Ẹ K'abọ

Nba dupẹ pupọ bi olotu bale gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin rẹ ti njade lojojumọ lati ki awọn ero Mẹkka ku abọ irin-ajo mimọ ti nwọn lọ ni alafia ti nwọn de ni alafia pẹlu.

Oje ohun ayọ ati idunnu fun mi opọlọpọ wipe ọpọ ninu awọn mọ Naijiria lo lọ si Mẹkka ninu ọdun yi. Awọn tolọ ninu ilewa ni Ijomu Oro awọn bi Alhaji Mohammed Adekanye mọkọkọ ki wọn na pe nwọn ku orire ti nwọn lọ ni ayọ ti nwọn si de ni alafia

Bẹ na ni mo tunki gbogbo awọ nyoku ti nwọn lọ ti nwọn si bọ pe, awọn ku orire o Ọlọrun yio ma moju to wọn. Awọn ti nwọn siku si Mẹkka Ọlọrun gba ẹsin wọn ki o si dari ẹṣẹ wọn jin wọn

Mo si ton ki Musulumi ile Naijiria pe wọn ku orire Ọlọrun alanu koni ṣe Mẹkka ni ewọ awọn Musulumi to ku o amin o

A salo-malekun

Emi ni
Yesufu Oyinlo ye

## Ilu Ikire Nfẹ Itọju

Olotu, inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ṣe aboju ilu Ikire ati agbegbe re. Ọpọlọpọ awọn ọna to gba ilu na ni ko si dara rara ati pe awọn ibi ti ọda wa gbogbo rẹ ni ọda rẹ si ti bere si kuro ti o si ti ojin koto.

Ilu Ikire si kuro ni ilu kekere ati pe ọpọlọpọ amọn nkan miran ni Ij ba ipinlẹ iwọ Orun ti ṣe ileri rẹ fun wa pe wọn yio se fun wa ṣugbọn nwọn ko ṣe ọkan ninu awọn nkan wonyi.

Eyi je ohun pataki to dun wa ni ile iwosan nla awọn ijọba ipinlẹ iwọ Orun sọ pe wọn yio kọ ṣugbọn ko si si nkan ti wọn ṣe sılu na ti awọn enia ilu na le fi ma dupe lọwọ nwọn

Inu wa yio dun bi nwọn ba le ṣe apojuto awọn nkan wonyi Mo dupẹ pupọ o Olotu.

Emi ni
John Idowu
IKIRE.

## Itumọ Ala

Agbaiọ— Ti o ba da owo fun alajọ tabi o gbowo lọwọ rẹ loju ala, Iwọ yio rin irin ajo kan laipẹ yi.

Abami enia— Ti o ba ri abami enia loju kun fun adura Ki aisan ma baa kọlu ọ.

Ayẹsi— Ti nwọn ba nyẹ ọ si loju ala, iparun mbọ kikan

Awokọ— Ti o ba nkọwe ni oju ala, sọra ki o ma ba lu ofin Ijọba.

Arọ— Ti o ba ri arọ loju ala Iwọ yio ṣe alabapade ohun rere laipe ọjọ.

Aisan— Ti o ba se aisan loju ala tabi ori ẹniti o nse aisan itumọ rẹ ni alafia ara ati anikuu owo,

Awo onjẹ— Ti o ba ri awo onjẹ loju ala tabi onjẹ ninu rẹ ṣọra gidigidi ijangbọn mbọ

**J. O. Shoyinka**
2/99 Shittu Street
Ibadan

## Iyipada Ile Iṣẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati lo ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan ki o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo Eran Itirẹ

## Apejuwe Ile Iṣẹ Wa

Ẹ Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni ti oba sokalẹ ni Lawanson, bere Ilu itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adiresi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

AWỌN IWE TI O WA FUN TITA

| | |
|---|---|
| Iwe Egbogi Awo Igba Arun | 20/- |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan | 25/- |
| Iwe Ala lati ọwọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara ati Etutu | 20/- |
| Iwe Ilana Yanrin titẹ ati Etutu Ṣiṣe | |
| Iwe Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati psalmu Ajẹbidan | 4/- |
| Lilo ati Agbara psalmu | 7/- |
| Turari Iṣegun Ajẹ ati Adura Tete damilohun | 10/6 |
| Iwe Akọmọ Lesin Islam ati Orisirisi Iwe | 1/6 |

J.O. Shoyinkan
c/o Postal Agent
Itirẹ Via Suru Lere,
Yaba.
or 1,Ishiba Street (Odo Ẹran)
ITIRẸ

## EGBOGI JEDIJED

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara re si nyọ o lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnse. Arun Jẹdijẹdi je ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma pọ owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukarna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu), pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnsẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ẹkeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taa igboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria. (Oja Ita Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

# Akan Joye Ọba Jomijoke

Lati Ọwọ ESỌ. AJEGUNLẸ.

Awọn ẹda ti o ngbe ilu Jomijoke ni awọn ẹda bi gọiu gọ, Ejo Erinmi, Ẹṣin-omi, Apanpa, Akan ati orisirisi awọn ẹda ti o ngbe oke ti o tun ngbe inu omi. Nigbati o ṣe awọn ẹda wọnyi pinnu lati ni Ọba.

Ni nwọn pe apejọ lati yan ẹniti nwọn o fi jẹ Ọba, Ajapa dide o pe awọnẹ.ranmi nlanla o wi fun wọn pe, kini ẹnyin ni fi oye Ọba ṣe, wahala ati ijangbọ sa ni oye Ọba E wa ọmọde kan ti o gboju ki ẹfi joye Ọba, nitoripe ọmọde kekere ni agba fi nse oogun igboju. nwọn si bere lọwọ Ijapa, tani on ro pe oyẹ ki o jọba na? Ijapa dahun wipe Akan ni on ro si.

Ẹṣin ọmi sọ wipe niti on. on ko faramọ Akan bikose ejo ni nwọn ba dibo ibo si mu Akan Bayi ni nwọn fi Ak... eyi ko dun mọ Ejo ninu, Bi Ejo ba ... Akan lọ si ode a... yan Akan ... ki Al... ni yio fi ẹjọ ejo sun ejo

Ni gbogbo igba ti Akan pẹlu ejo ba nlọ si ode ni ejo ma a njin Akan lẹsẹ. Li ọjọ kan Akan sọ fun ejo pe gbogbo jamba ti nṣe fun on, ri patapata. lọjọ ti baba on ba gun on bi gbogbo aiye bẹ on, on ko ni gbọ.

Inu bi ejo, o sọrọ fun Akan wipe, kini Akan le se fun on. Bi o ba fẹ, kio jade wa ki awọn jijọ ja

Akan sọ fun wipe, lọjo ti o on yio ba ja, ninu ile rẹ ni yio wa ba a. Ejo ti gbagbe pe ọba ni Akan, o ... mẹsan ... lo

Ni alẹ ọjọ kan ti ... regbe ti egderegbo ti gbogbo ara Ilu Jomijoke ti sun Akan jade, on nikan ... inu iho lọ ba ejo o si baa nibiti o suu si

Ni Akan be fi iga kekere kan mu ejo lọrun o mu ni amudiju pẹnpẹ.

Ejo gbija, o gbe Akan sanlẹ, pẹn, pẹn, pẹn Akan mu nigbati ejo ko ri aye mi mọ lo ba ku silẹ gbalaja ati ọjọ na wa, bi ejọ ba gburo Akan ere asajugbanu ni yio sa, nitor na eru ko ba Akan ẹniti o ṣe akan ni ka Oluwa rẹ ni ẹbọ mbọ.

## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun To bọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWA RẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa ọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi oya nitori IWO NI ỌBA alagbara Olubor gbogbo ẹda patapata" Amin.

**WAS SALAM"**

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ... oyẹ ki o ri Ana lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AGUARIUS (Jan 22-Feb 20) Iwọ o ri owo lo loni, iṣẹ ti iwọ pẹlu eni kan jijọ se pọ yio mu ere wa jabrata

PISCES (Feb 21-Mar 20) Iranlọwọ ti o nfẹ yio de laipẹ lati ọdọ en a pupa ṣọra maṣe tako wọn rara, bi o ba de.

ARIES (Mar 21-April 20) Ayipada ojiji yio de si ọ, ṣugbọn ṣọra ki o ma ṣe ju ara rẹ lọ, Iwọ yio ri iṣẹ ṣe ju atẹhin wa lọ suru li ẹbọ.

TAURUS (April 21-May 20) Maṣe yara kankan ati se nkan, nitoripe bi o ba lọ ṣe bẹ, iwọ yio ke abamọ rẹ lẹhin wa ọla.

GEMINI (May 21-June 21) Ọgbọn rẹ dopin gbogbo rẹ su ọ gọọ ohun to dara fun ọ ni pe, ki o lọ wọran nibiti nwon gbe nsere, ki o si ba wọn korin ki ara rẹ ya eyi ni etutu.

CANCER (June 22-July 23) Eṣe ti o fi ngbọn, maṣe gbọn rara nitoripe ko si idi ti o fi ni lati ṣe bẹ ma bẹru ṣe ohun ti o fẹ ṣe iwọ yio si ri daju pe ohun to mba o lẹru fo lọ

LEO (July 24-Aug 22) Lọ din iwa buruku rẹ ku maṣe bikita yala awọn enia nfi ọ ṣe ẹlẹya lati wo kini iwọ yio ṣe Iwọ o gba alejo kan lọna iyanu lalẹ oni.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Li owuro ọjọ oni ọrọ inawo kan yio ṣẹlẹ si ọ, ṣugbọn ko ni pẹ kuro nigbati owo gọdọ yi ba de oju owo apo rẹ ki o ma ba na inakuna.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Iwọ yio gba isimi fun igba diẹ ṣọra nitori jamba ewu ona.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) ... rọ amoju rẹ, ni yio le awọn ti o ṣe pataki ninu awọn ọrẹ rẹ sọnu, ṣugbọn ọkan ninu wọn yio duro ti ọ nigba wahala ati nigba ewu

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Lojojumọ, li o ma nwo ara rẹ pe kosi bi iwọ ko ti ri, Alejo nla kan yio wa ṣe abẹwo rẹ.

CAPRICORN (Dec 23-Jan 21) Jẹki ọkan rẹ le, ki o ba le ba ... kunkun ti o fẹ bo oju arisiki rẹ mọlẹ yi jagun, ṣọra ki o ma gba adura ki o ba lẹ ṣẹgun okun kun na.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALẸ-BI-ELE Egbogi Toniki wọn Jamonu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣe ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa da ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inn ko ba gunlẹ darad rawọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn alera gbogbo eyi il ọjọ ori rẹ (age) ba ti koja Ọgbọn ọdun lọ si ded'adẹtin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara b otun patabata, oju rẹ a si jọlọ, ṣran ara rẹ ti a ti huujọ yio bẹ rẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba d'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igbadun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu:-

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Stree, Lagos.
ADEDUN CHEMISTS'
14, WAKEMAN STREET YABA.
ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# Asọbade Orire Ere Bọọlu

SCOTT, SUMMER CUP.
Dundee U. v. Aberdeen 1
Falkirk v Hiberian x
Hearts v Dunfermline 1
Kilmarnock v Airdrie 1
Motherwell v Queen of Sth 1
Patrick v Morton 1
St Johnstone v Dundee x
St Mirren v T. Lanark 1

NEW SOUTH WALES
Adamstown v Maitland x
Bankstown v Corinthians 1
Canterbury v Croatin 1

QUEENSLAND
MERton v Coalstars x
Oxley v Hellenic 1
Annerley v Germania 1
Taringa v Dnipro 2
University v Easts x

VICTORIA—DIV 1
Box Hill v Richmond x
Coburg v Sandringham x
Croatia v Oakleigh 1
Makedonia v Baywater 1
Moreland v Dandenong 1
Sunshine C v Austria 2

VICTORIA—DIV 11
Collingwood v Flinders 1
Ferntree v Park R 1
Libertas v S Yara 1
Prahran v St Albans 1
University v Moonee 2
Williamstown v Brighton 2

VICTORIA—DIV 111
Heidelberg v Frankston 2
ICI v Croydon x
Moorabin v Rosebad void x
Northcote v Sunshine H x
Ringwoo v Essendon 1
Trident v Spingvale 2

S. AUTRALIA.— DIV, 1
Budapest v Hellas 1
Craotao v Birkalla 1
Cumberland v Juvendus x
Polonia v Enfielli x
Victoria v AustraDa x

S, AUSTRALIA— IV 11
Beograd v WRE 1
Edinburgh v Napo li 1
Malta v P Adelaide 1

Orange v Lion 2
Salisbury v Elizabeth 5

W. AUTRALIA STATE
Anthena v Windmills 2
Azzurri v Swan A x
N. Perth v Spearwood 1
Olympic v Cracovia 1
Aswan V v Tricolore x

W AUTPALI4-DIV I
Brittania v Perth C 1
Caledonia v Julia 1
Cottesloe v [illegible] 1
Emu v Maccabean 2
M. Juventus v S. Perth 1

W AUSTRALIA-DIV 11
Macedonia v University x
Medina v Sibbiano 1
Queen's Pk v Bayswater x
Scarboro v Balkan 2
Vastese v Sports void

TASMANIA LEAGUE
Croatia v Caledonia 2
Olympia v Eagles 1
Rangers v S Hobart 1
Rapids v Juventus 1

## Selections

My selections for the Homes list are: Kilmarnock Motherwell, Annerley, Macedonia Collingwoob Prahkem North Perth Rangers Malta Caledonia Medina Ferntree Rapids.

My full selections for the Cricket Treble chance are Livingstone — M, Hill Bernard Whittingham Close Cowdrey Boycott—Luckhurst Barrington Burge Willett Booth Bennett — Pressdee, Cart wright Hallam Stewart W-Innam

# Abajade Orire Ere Bọọlu Ọsẹ To Kọja

REPRESENTATIVE MATCH
N.S, Wales 1 Everton 6

N.S.W. NORTH. DIV. 1
Mayfield 2 Adamstown 3

HOBART LEAGUE
Calies 0 Juventus 1
Eagles 0 Rapids 7
Olympia 3 Rangers 0
South Hobart 1 Croatia 5

BURNI LEAGUE
Devonport 5 Celtic 3
Spartans 2 Rovers 3

VICTORIA STATE LEAGUE
Alexander 3 Lion 2
Melbourne 2 Juventus 3
Pol nia 2 Withelmina 4
Slava 1 Hakoah 0
S. Melbourne v JUST Postponed
Triestina 0 George C. 1

VICTORIA DIV 1
Austria 0 Croatia 1
(abandoned at half-time)
Bayswater 1 Sunshine C 2
Dandenong 1 Box Hill 6
Kleigh 5 Coburg 2
Richmond 1 Makedonia 2
Sandringham 1 Moreland 0

VICTORIA DIV. 11
Brighton 1 Libertas 2
Flinders 2 Prahran 3
Mooree P. 1 Collingwood 1
Ph. Rangers 1 University 4
South Yarra 1 Ferntree 2
St. Albans 1 Williamstown 2

VCITORIA DIV 111
Grovon 2 Heidelberg 0
Essendon 2 Moorabbin 0
Frankston v Trident unplayed
Points awarded Franssion
Rosebod v Northoote unplayed
Points awarded Northcote
Springvale 2 Ringwood 1
Sunshine H 1 ICI 2

VICTORIA DIV IV
Alax 2 Glenray 0
Flemington 7 Melita 2
Helvetic 0 Albion 3
Mooroolbark 2 Hercules 2
Tullamarine 1 Chelsea 2
Waverley 11 Huntinadalle 0

QUEENSLAND STATE LEAGUE
Hellenic 2 Redbank 1
Latrobe 3 Merton 3
Thistle 2 Azzurri 1

QUEENSLAND DIV I
DniPro 2 University 5
Germania 5 Southside 4
Hollandia 5 St Helens 2
Postal 1 Taringa 7

SOUTH AUST DIV 1
Austria 4 Budapest 5
Birkalla 0 Juventus 3
Croatia 3 Victoria 4
Enfield 2 Cumberland 1
Hellas 3 Polonia 4

SOUTH AUST DIV 1
Elizabeth 3 Beograd 1
Lion Adelaide 0
Napoli 1 Salisbury
Orange 2 Edinburgh 2
WRE 1 Malta

# Iṣẹ Awọn Iwe Irohin Larin Ilu

LATI OJU EWE KEJI

Nitori a ni lati ran iwe Irohin lọwọ olukaluku ni ilu nipa ti nwọn la ti sa fun ifarada fun ara eni lati ni eni ododo ninu iṣe ti ologo yi.

Ko si ohun rere ti a le mu ade ninu Iwe Irohin ti a ba nta eri ọkan rẹ ninu iṣẹ Iwe Irohin. Iru iwa yi ko le mu ogo ba Iṣẹ Iwe Irohin.

O di gba diẹ na o.

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe gbeyawo
TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ERỌ ITẸWE
Modupẹ Printing Press
16. Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ERỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO FOJUB
Dan wa wo lẹẹkansoso ki o ri iyatọ

# IWE ITUMỌ ALA

Josefu Alala ti ẹ ti nkan ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo.
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ ti o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun.

Iye owo 5/- £2

tabi

1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ,
Via Suru—Lere,
Yaba

# Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbe Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹwa oṣu karun (10/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipapẹ lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Akọwe Agba

